the Chief Secretary to the Govern...


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. II. No. 83. SATURDAY, FEB 9. 1924. Fourpence.



## DURO THOMAS.

55, MASSEY STREET, LAGOS, (NIGERIA)

P.O. Box 374. Telephone No. 243.

*The Best House for every Description of German Goods.*

"Specialities: Enamelware. Beer. Wine. Iron Bedsteads. Ruby Plates. Rubber Beads of all kinds. Clay and Briar Pipes. Champagne. Cement. Biscuits in cases. Gun Powder. Wire Nails Raugoon and original Ballam Rice. Accordeons. Piano. Padlocks. Beads etc., etc., etc."


**Circulation 1,000 Copies Weekly.**

EGBERUN IWE-IROHIN YI LA NTE LOSOSE.


N. V. HANDLEMATTSCHAPPIJ V.H.

**J. F. SICK** ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laibi, l'eti *Glover Memorial Hall, (Custom Street,)* EKO.





Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșe Masini-Aranso ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọiwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati șe adehun pataki pelu ẹnikẹni to ba fẹ ranșẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu Masini na.

Awọn Oyinbo yi nșe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati paru kikele to nipọn, ati ẹja abọmalọ ati orișirisi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ Asiri nipa Owo. Irohin ko to afojuba.

## J. C. VAUGHAN

Ti Ile-Qja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Qja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ọkọle fun tita ni owo opoku-oyoku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni OGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

OKO tita w ... ni owo po o.

## B. O. Joseph

*Commission Agent.*

21 years experience in trade.

**Cotton.**

**Sundries.**

**Hardware.**

**Provisions.**

27, Koseh Street, Lagos.

**Cable Address:—**
"Steinafrik" HAMBURG.

## E. H. STEIN & Co.

**HAMBURG, Neurwall 16/18.**
**Hildebrandhaus.**
*AFRICAN MERCHANTS.*

**ALL INDENTS EXECUTED.**
for
English and Continental Goods
and
PRODUCE
Sold on Best Terms.

**Produce to Europe covered by Floating Marine Insurance Policy.**
*P. O. Box No. 505.*

Agent in Lagos :—
**Mr. Karimu Kotun**
Broad Street, & Portonovo Market Store.

## FOR SALE.

One secondhand Harmonium with 4 Octaves.
*Price Moderate.*
Apply to Mr. A. ONIORISAN
c/o P. Z. Lagos.

## BULL WEST AFRICAN LINE, INC.

AWỌN ỌLỌKỌ TI IJỌBA AMẸRIKA

Ọkọ elefi awọn Oyinbo wọnyi nko ero ati ẹru ni Iwọ Orun Afrika, ni oşoşu o si ngba ero lọ si ilu Amẹrika ati awọn ilu miran pẹlu. Ọkọ wọn yara, owo pọ ni nwọn si ngba. Ẹnyin ero, ẹnyin onişowo Obi, Koko, Ekurọ ati Epo, ẹ lọ ke si aşoju awọn Ọlọkọ yi ni :— Oke Pẹtẹsi ile *Colonial Bank*, ni Ẹhin Igbẹti, Eko.

## ERO YA WA RA.

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" ni Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Iṣo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun-ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Ile-ọja rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

OWO ỌJA RẸ FANIMỌRA.
Ẹ LỌ RA TIYIN NIBẸ.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 22 & 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|
| Ọdun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Ọṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Ọṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

KATAKATA MA MA F'EṢIN TẸ MI!!!

Bi awọn onijo kan ti njo ajo-yi-po agbo ni Oke Suna ni *Saturday* to kọja, bẹni ẹlẹṣin kan ja eṣin rẹ lapa ibẹ, a ko si mọ bi o ti gun eṣin na ki o to lọ tẹ ọmọde kan lapa ti o si ṣe leṣe, nipa fifọ egungun apa na; pẹ-ntuka ni agbo ṣe ti olukuluku du'na, o di b'ō lọ, o yā mi.

O jẹ aṣa awọn ẹlẹṣin miran lati ma pa enia laiya, nipa jija eṣin wọn kutupa-kutupa nigboro; o ṣẹ ndi igbagbogbo awọn irufẹ enia bẹ, a si kẹ si awọn Ọpa Ọba, ki nwọn ma ṣai ṣe ni lọwọ awọn Ag'eṣin-ko'la wọnyi, fun irufẹ iwa fāri ẹlẹtẹ ti nwọn nṣe na. Ki a si fi ofin ki wọn wọ nipa ki a ba nwọn ro'jọ ni Ile Baba Ẹgbẹ ni Ita Tinubu, nipa bayi nwọn yio mọ pe epopo-ode wa fun ẹnikẹni lati rin, kiṣe fun kiki awọn ti nwọn ngun ārúkọ ti nwọn nnwọn ng'eṣin!!!

OGBẸNI BABINGTON OLUMUYIWA, O KU AGBA!

Iku Ọgbẹni Akinlawọn Olumuyiwa ni Ilu Oyinbo *England*, ẹgbọn ọrẹ ati ẹlẹgbẹ wa ni Ile-iwe giga kanna ti *C.M.S.* (*C.M.S. Grammar School*) ni'leyi ti o si di Ọga "Ai-ko-nla" (*Accountant*) ni Ile Iṣẹ Munisipa nisinsinyi, mu ni ranti iranlọwọ ti ologbe na ṣe fun awọn Ẹgbẹ Ọmọde-mọṣọ Ijọ *Bethel* (*Youngmen's Bethel Church Association*) ni ọdun kejilelogun to kọja nipa lilọwọ si ere Oyinbo kan ti awọn Ẹgbẹ na ṣe ni Ile Iranti Afari Ogun l' Ẹhingbẹti fun iranlọwọ Ṣukuru Ijọ na ni akoko yi. A npe ere na ni *Shakespeare's Richard II* ipa ti ologbe yi si mu ni ti Ọgbẹni *John of Gaunt* ninu ere na; Ọgbẹni ologbe Josephus Taylor kekere, lo si ṣe Ọba *Richard* keji na, oriṣiriṣi aṣọ ti ologbe yi da pẹlu ologbe Josephus Taylor fun ere na ná wọn lowo lọpọlọpọ laika aṣọ ti awọn jakan-jakan miran fun da pẹlu awọn bi Ọgbẹni Ojo Cole, Ọgbẹni Kusika Taylor, ti o niẹ Jacob Jones nigbana, Ọgbẹni Josephus Vaughan, Ọgbẹni E. Bankọle Beckley, Ọgbẹni Akin Adeṣigbin (Tika-iore) Ọgbẹni G. I. Adewale Vincent ati Ọgbẹni Eman Ṣowọnọla. Iya afin Mrs. Okuyiga ni o ṣe Ayaba nigbana, Iya afin Sabina Romọṣe Williams ti o di Aya H. Ọlatunde Glover, Iya-afin Miss Cole ẹgbọn Pastor Adedeji Iṣọla ti o di Mrs. J. F. Kufeji nisinsinyi, si lọwọ ninu ere yi.

Aya Oyinbo Olori Ile Owo nla *B.B.W.A.* Mrs. C. Tambaci ni ẹniti o joko lori aga lọjọ na; Ọgbẹni A. W. Thomas si ni Baba Ẹgbẹ awọn ọmọde mọṣọ yi lakoko na nigbati a ko owo jọ, fun ere na, a ri to ọgbọn pọnun (£30) lẹhin igbati a si yọ owo inawo gbogbo kuro, o ku ogun pọnun (£20) ti a fi ta awọn Igbimọ Ile Iwe *Bethel* na lọrẹ: o dun mọ Baba Ẹgbẹ A. W. Thomas ninu tobẹ, nigbana to fi se ase rẹpẹtẹ fun awọn ọmọ Ẹgbẹ rẹ yi ni ile rẹ ni Ọnaṣokun ni Opopo-nla l' Eko. Ọgbẹni Adol Adediran Coker ti Ile Owo nla (ologbe) ni Sẹkitẹri ere yi, Ọgbẹni Adeoye Deniga si ni Sẹkitẹri Ẹgbẹ na. O ṣe! ọjọ nlọ a nto o!!!

Oṣu *October* 1902 ni a ṣere na, Ilẹ kun akunya, t'Oyinbo t' Enia Dudu. Ki Baba ma ṣai f'oriji awọn Ologbe wa wọnyi Amin.

Ọgbẹni C. Babington Olumuyiwa, o ku agba, o ku afẹku. Ki Oluwa ma ṣe ọ laṣọ, Aṣẹ.

## EGBE TUNLUṢE NGBILẸ.

Ni *Saturday* to kọja a ṣe Ipade gbogbogbõ ti Ẹgbẹ Tunluṣe l' Ẹhingbẹti ninu ọrọ ti a sọ fi han pe awọn ọmọ Ẹgbẹ na le ni ẹgbẹ̄dogun enia ( *over 3,000* ) nisinsinyi a si sọ pe ọgbẹni kan Suberu Dawodu ti o jẹ ọkan ninu ọmọ Ẹgbẹ na ṣãyan o si gbin Ẹka Ẹgbẹ na silẹ ni Ipaja ni agbegbe Agege, ati pe awọn kan nsapa nisinsinyi lati gbin Ẹka miran silẹ ni Agbadarigi ; Sẹkitẹri Owo Ẹgbẹ Ọgbẹni A Bank Anthony jihin pe owo Ẹgbẹ na ti on fi si *Bank* jẹ pọnun mẹrinleladọsan (£174) laika awọn ileri owo miran ti awọn to ṣe wọn ko iti muṣẹ. A si mu iwe ti awọn *Congress* kọ si isọri-isọri Ẹgbẹ na wa si Ipade, gbogbo Ipade si f'ohun ṣọkan pe bi awọn Bọkini ti *Congress* ti nwọn ni nwọn mbọ wa na bade, ki Ẹgbẹ gba wọn tọwọ-tẹsẹ. A si sọ pe a o ka awọn ibere ti awọn Ọlọla ti a yan si Igbimọ Aṣofin Ọba yio bere ni Ipade Igbimọ ti a o ṣe lọjọ kọkanla oṣu yi, fun Ẹgbẹ laipẹ.

## ADAJỌ ỌRẸ EWE, Ẹ KO ṢA F'ARAPA?

Bi Weber Ọlọla, Igbakeji Adajọ Agba ti nti Kõtu lọ sile, lori kẹkẹ ologere rẹ niwọn agogo mejila-abọ ọsan *Wednesday*, Alaruba, ọsẹ yi, ti o gba Opopo-nla, bẹni ọmọdekọnrin kan ọmọ-ile-iwe ṣẹ yọ lati Ita Kakawa leti Ile *Cinema* Oyinbo Ọgbẹni Pickles to si kọlu Adajọ yi, o di wo-ngangan ni'lẹ, bẹni bọ̀bọ́ fi si nigbati ẹru ba ; Ọlọpa Adajọ na *Orderly* si gbale ọmọ yi lati mu, ṣugbọn Adajọ oninure na pe e pada pe ọmọ na ko mọmọ kọlu on, bẹni Egunlẹgi dide to tun kẹkẹ rẹ ṣe, to si gb'ọna ile. O ṣeun Adajọ Ọrẹ Ewe iwọ a jaiye pẹ !

## Ẹ KU 'KESI, ỌMỌ BALOGUN OGUNBỌNA, A-GBOKE T'OYINBO !

Baba wa Bishop Howells, ke si wa ni *Office* ni *Wednesday* ọsẹ yi, o si gba wa niyanju pupọ nipasẹ Iwe-irohin wa "*Eko Akete.*"

Ẹni-ọwọ-nla yi jẹri si ẹgbagbeje awọn enia ti nwọn nka "*Eko Akete*" o si f'ọrọ we ọrọ fun wa nipasẹ rẹ . eyi wu ni lori lọpọlọpọ. Ki Ọbangiji Ọla-ogo ma ṣai s'ẹnu nyin siwaju fun wa, Aṣẹ.

## AWA ỌMỌ AFRICA ṢE NMỌ IYI ARA WA DIEDIẸ !

Awọn Igbimọ ọmọ Ile Iwe Giga atijọ ti *C.M.S.* ni'lẹ yi *(C.M.S. Grammar School)* ṣe iyẹsi àtà fun Bishọp Oluwọle ni *Wednesday* ọsẹ yi nipa tita lọrẹ Aworan rẹ ti a ṣe ni'lẹ yi ; awọn isọri-isọri enia si sọrọ nibẹ ṣugbọn a ko le ṣai sọ ti iwa to jọ iwa anikanjọpan loju wa, ti awọn Igbimọ na hu, nipa fifi kokari iṣẹ ribiribi yi di ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ-ile-iwe na atijọ l'eti.

Iwa yi ku diẹ ki o to.

## OYE A MỌ NYIN LORI O, ẸNYIN "APẸJA ENIA."

A ba Alufa S. A. Pearse ati Dada ti Ijọ *Wesley* ni'lẹ yi yọ fun oye Alufa kikun ti a fi wọn jẹ ni Ile Isin Ijọ na ti Ita Tinubu ni *Tuesday* ( Atalata ) ọsẹ yi ; Ẹ gbere, Ọga-ogo a gbe nyin !

---

## BRỌDA, IWỌ KO ITI MỌ ỌNA O NDA PADEPADE ATARI AJANAKU HA NṢE ẸRU ỌMỌDE BI? AGBẸDO.

Laisi aniani, ninu iwe rohin "Eko Akete" ti oṣu 26 *January* ni agbe ti ri ka nipa ede aiye ede ti o wa larin Ijọ Ebenezer ati alufa rẹ—Rev. Charles Alabi.

Ibajẹ ohun ti o dun ni pupọ bi o ba ṣe pe ọrọ alufaṣa ti a sọ sinu rẹ jẹ ọrọ lati ẹnu ọkan ninu awọn alagba Ijọ na wa ni. Ṣugbọn nigbati a wo gbogbo ọrọ na gbã, aridaju pe ohun ti a sọ nibẹ jẹ ọrọ alairi iṣẹ ṣe, ati pe ofutufẹtẹ ni (*Idle invention*) ko si wa esi kan rara ti a ba wo ipo ẹniti o nsọrọ ati ẹniti a sọ si lara. Ṣugbọn Awọn baba wa a ma powe wipe "Bi a ko ba yọ ipin loju ka fi han, oju ko ni mọ pe on ni ẹgbin lara," eyi lo mu ki a fesi kekere yi sinu Iwe-irohin.

Laisi anini, alagba ara America ti a gbun sinu iwe na jẹ ẹniti iṣẹ rere rẹ han larin Ijọ na, ati pe ki iṣe nibẹ nikan ṣugbọn larin ilu rẹ pẹlu. Ẹnikan losi mọ iwa iru enia ti ara America na iṣe.

Ni ṣoki mo fẹ sọ fun gbogbo ẹnikẹni ti o nka iwe Rohin na pe ifijẹ Oye Alufa Alabi jẹ ohun ti ẹnikẹni fẹ ( boya ọdọmọkunrin alatako yi ko fẹ ) ki

alagba ara America na to wa ni ọwọ ninu rẹ nigbati a sọ fun pe ki o ran wa lọwọ.

Awa ti o si fowọsinu iwe nigbana lai ka awọn obinrin ati alagba Iọ le ni adota ọdọmọkunrin ti ero wọn pe dada. Lẹhin eyi o sa gbogbo ipa rẹ a si fi ọkọnrin na jẹ Oye Alufa "Kini ewurẹ ṣe to li d'ọta Oyinbo"? Laisi anini mo rope ẹgbọn ẹniti o kọ iwe atako na jẹ ọkan ninu awọn ti o fa Charles Alabi wa sinu Ijọ Ebenezer, ti o si ro li akoko na pe o ṣẹ ki Ọgbẹni Alabi jẹ Oye kan ninu Ijọ.

"Ija lo de l'orin d'ewe," ẹjẹ ki a fi keta gbogbo silẹ kọkan wa si kun fun ifẹ; ki a fi iwa unẹlẹ, tembẹlẹkun aitẹ ọmọnikeji ẹni ati arankan gbogbo ti o ti wa lati igba iṣedale Sọsi na silẹ, ki a si mọ wipe, "Bi omi titun ba ru, o yẹ ki ẹja titun ki o wọ."

Yio ya ọpọlọpọ enia lẹnu wipe esi gàn ti o yẹ ki a fun ẹniti o kọ iwe atako na kọ li a fun ninu iwe yi: tōto ni. Owe kan lo bayi pe "Aṣapẹ fun were jo, on ati ẹ jẹ ẹgbẹra." Ọrọ diẹ to fun ọlọgbọn. Ọkunrin jẹjẹ abija kikan lo ko iwe yi ẹniti a ran lọ si ile ẹko to ga julọ li Eko ni, ti o fi ni ero lori perepere. "Aki gbọ ibi lẹnu aborẹ" ganranganran ko yẹ ọmọ enia mo bẹ ọ Broda, lọ paro inu rẹ o pọdọfin inu rẹ ki o pa iwa rẹ da lọdun titun yi.

AMERICA KEKERE.

## FACTS AND FIGURES

### West Africa's First Mohammedan Barrister.

#### A Phase in Moslem Education.

If it were somewhere down Georgia, Texas or North Carolina—in the lands of Stars and Stripes the small but unique gathering of enthusiastic people that took place in front of No. 62, Bamgbose Street on the 28th of last month could have from appearance been unmistakably taken to be a night parade of the K.K.K. !!!

This not being the case the present gathering had behind it a motive which must be lauded by all and sundry.

Mr. L. B. Agusto, First President of the Ahmadia Movement in Nigeria and first Moslem Barrister in the whole length of British West Africa, was called to the Bar that particular evening and it was deemed necessary to make a demonstration to honour the "call."

Dr. O. Sapara I.S.O. in his opening speech (on the ocassion) pointed out that it was not only because this gentleman was called to the Bar as many worthy sons of the soil have been called many a time before him but because Lagos has been the first to produce a Mohammedan Barrister in the whole of West Africa an honour—nay, a sign of progress—that will reflect not only on the Mohammedan community but on the country as a whole. At the end of a brief but interesting speech Dr. Sapara fired a rocket to demonstrate his joy.

Mr. L. A. Cardoso followed this with another brief interesting speech. He said among other things that Agusto is a Mohammedan because he was born in religion and he (Mr. Cardoso) a Christian because he was born in Christianity; so it is the fault of neither of them to belong to different religions. We were first born before we take a religion and there is no reason why religion should debar us from our national duties.

The two speeches were followed by loud applause and a grand display of fireworks which lasted the best part of the evening.

This is no doubt an interesting phase in local Mohammedan education and—though Rome was not built in a day—we earnestly look forward for the day when the Mohammedan Community will have its own band of Lawyers, Doctors, Civil Engineers, etc., etc. Those would be happy days when there will be no *Mohammedan Crisis* at least of the kind presently in existence—a time when an intelligent, educated and consequently law-abiding Imam shall have to submit to the orders of the majority, a practice obtaining in all enlightened societies.

Readers of this paper are hinted last week of the impending arrival of Mr. L. B. Agusto and we sincerely hope this energetic and painstaking gentleman will be given a welcome which will befit his score. Let the Ahmadia Movement start making arrangements from now. Let all educated Moslems in town whether Ahmadia or not prepare to give him the receptions that he deserves. Nay, let the Christians, the well-meaning Christians, who believe they were born Negroes first before they are Christians prepare and receive this personage with as much liberality as their broadmindedness can permit.

In fine, we must commend with all sincerity the spirit which has inspired men of the positions of Dr. O. Sapara and L. A. Cardoso to organise or take part in a demonstration such as that of the 28th of last month.

It is that celebrated poet, Rudyard Kipling, who said: East is East and West is West; and the twain shall never meet. We hope that this, to day, cannot be applied to Christians and Mohammedans in Lagos nor can it apply to any one Negro and another.

ADEKANBI.

The Editor,
Eko Akete,
Lagos, Nigeria.

Dear Mr. Editor:

Please allow me to bring to the notice of the C.M.S. on your golden Library, matter affecting the Scripture Union Celebration.

It is stated that the Scripture Union Mission started on 1st April, 1879, but to my surprise, it has not been put to practice to celebrate her Festival as others such as Lagos Church Mission etc.

Will the C.M.S. please decide?

Thanks Mr. Editor for space allowed.

Yours in spiritual scene

S. B. A.

**EKO AKETE.**

EKO, SATURDAY, FEBRUARY 9, 1924.

## OWO O, IWÓRÒ, OWO !!!

Kosi ọmọ Ẹgbẹ kan to wa si Ipade Ẹgbẹ Tunluṣe (*Nigerian National Democratic Party*) ti *Saturday* tokọja, ti ọkan rẹ koni gbọgbẹ nigbati Ọgbẹni wa Herbert Macaulay nṣipaya lẹsẹsẹ oniruru owo Ilu ti Ijọba npete ati na, owo miran fun titunkọ Ile Oyinbo si, owo miran fun nina loriṣiriṣi ọna; o si wa sọ olubori rẹ pe owo ti Ijọba wa nibi npete ati na, ti o jẹ inawo ọdọdun (*Annual Estimates*) fun gbogbo iṣẹ oba, le ni Adọta ọkẹ poun ọna m run (*over £5,000,000*) Ọgbẹni wa si tun sọ ti ọkẹ poun kan o le Ọdẹgbajọ (*£35,000*) ti Gomina ti ya sọtọ fun nina fun iworan Arakniyamu (*British Empire Exhibition*) ti Ilu Gẹsi nṣbero lati ṣe ninu oṣu *April* ọdun ni titi de oṣu *October* rẹ. Laisi aniani, owo ti t'emi tirẹ ti t' Oyinbo t' Enia Dudu jakejado gbogbo Ilu *Nigeria* nda s'apo Ijọba leyi, ọna ti Ijọba yio gba na awọn owo wa yi ti ki yio jẹ nina ti oninakuna, tabi ti ofomi-ọ̀jọ̀, ni awọn Aṣoju wa ni Ajọ Igbimọ—awọn Ọ̀ọla Ọgbẹni J. Egerton Shyngle, Eric O. Moore, ati Dokita C. C. Adeniyi Jones—nlọ sọ ka si n'kan ọrọ nipa rẹ lotunla (*Monday*) nibikanna ti a g e ṣe ipade na ni iṣiwaju.

Iṣẹ ti awọn Aṣoju wa nwọnyi pẹlu awọn Aṣoju Ilu miran bi Calabar, Onitsha, Opobo nlọ ṣe nibẹ kiṣe iṣẹ yẹpẹrẹ; ọmọ-ana papa mọ pe o jẹ aṣa Ijọba lati mã na owo ilu yã fun awọn Oyinbo ẹlẹgbẹ wọn—Ẹnyin ẹ tun ka ohun ti a sọ lẹnu ọsẹ diẹ sẹhin nipa fitìnátì ti pupọ ninu awọn enia wa to jẹ ọmọ *Africa* nri nigbati Ijọba ba ran wọn lọ s'ajo lati ṣiṣẹ, gẹgẹ bi o ti jẹ pe Ijọba kĩ bikita lati wá tabi pèsè ile ti nwọn mã gbe ti nwọn ba de ibẹ, ṣugbọn ti awọn Ijọba kanna kĩ kọ lati tẹ Oyinbo k' Oyinbo ti nwọn ba ran lọ ṣiṣe l'ajo lọrun bakanna lara owo ilu ti t'emi, t'irẹ njọnda yi, a si sọ ti ọmọ jọgọlọ ni, Ọgbẹni Daniel Atitẹbi ti o ti nṣiṣẹ ni Ile Owo Iṣura nibi (*Treasury*) ti Ijọba ran lọ ṣiṣẹ ni ilu awọn Dewo (*Port Harcourt*) lalai pèsè dẽ, ti otutu si rọ si ọdọmọkọnrin na laiya, ti o si ba bẹ̃ di ero-ọrun, laitọ oṣu meji ti o f'Eko silẹ !!!

Gbogbo irufẹ iwa ti ko wọ bayi ni awọn Aṣoju wa yi yio mu wá siwaju awọn "Alaiye" ninu Ipade ọtunà na, nwọn yio si sọ kulagbe ọrọ fun Ijọba nipa ohun pupọ ti nwọn yio bere lọwọ wọn fun anfani ilu.

Awọn ọrọ bi fifẹ Ile Iwe Giga ti Ọba *King* ni'lẹ yi (*King's College*) ọrọ ti Ọlọla Ọgbẹni Moore ṣi wa lẹnu rẹ gbágbá tabi ṣiṣi Ile Alarun ti Ereko iṣẹ eyiti Ọlọla Dokita Jones ni ki a fi le on lori te, tabi titun ofin Kotu Igberiko ṣe, iṣẹ eyiti Ọlọla Shyngle ko jafara si, ati ọpọlọpọ nkan bawọnni.

Asiko yi kuro ni asiko a-nbu ara ẹni ni a-boju, a-bimu, o si yẹ ki ilu—papaawọn ọmọ Ẹgbẹ Tunluṣe—mọ pelisẹ nlanla ni Edumare pe wọn si lati ṣe fun rere ilu *Nigeria*; ki a si mã fi ọkan kan ṣẽ la boju w'ẹhin, ati lati ma fi ãyan wa, wiwa si Ipade Ẹgbẹ dede wa, adura wa, itara wa, ati ifẹ wa ran awọn Aṣoju wa mẹtẹta na lọwọ tobẹ ti nwọn ba ke si wa pe Abẹyọ? Ki a maṣe lọra lati dahun pe :—

Abẹ'yọ jẹ !!!

---

**FREQUENT DEATHS OF YOUNG PREGNANT WOMEN IN TOWN.**

***A case for our Medicos,***

SAVE THE POPULATION !!!

The apparently high-rate of mortality amongst our young women with child noticeable to those who have eyes to see, and ears to hear in these days, is so alarmingly frequent as to cause us to pause and ask ourselves the question—What is all this about?

If ever there is a time in which the *unstinted services* of our town Medicos are *badly needed* to unravel this problem which is unhappily bringing wailings and "gnashing of teeth" in its train, surely, this is the time.

We earnestly call the attention of the Government to this deplorable state of affairs which is nothing short of a bugbear in the community.

## ṢAGO NBU IGO.

[*Lati ọwọ* ATARI AJANAKU.]

Si Oni 'we-irohin "EKO AKETE."

Mo bẹrẹ f' oji,

Ko si ohun titun labẹ ọrun. Ajepola npe ologbo ni abeṣe, ole npe oni nkan ni ọlọṣa, panṣaga nwijọ pe abiamọ ko joko jẹjẹ, oloraye npe oṣiṣẹ ni alapa-mașișẹ, apa bobo, afoun-fọra npe olowo ni amuṣua, abọrișa nkanu pe Kiriyo ati imale wa ninu okunkun, alagbawa to nwa Moto npe o ni Moto ni gongoṣu, ọmọ ile iwe npe olukọ rẹ ni akọwe Alagbọn, ọmọ npe iya rẹ ni danosungbo nitori "kẹntoki" to wa ni ẹrẹkẹ rẹ, ẹniti ko ri owo fi ra agutan nkẹgan ẹlẹṣin, alafọfun npe ajilaran ni Jinọdu ẹlẹṣọ, Ṣago npe Igo l' ọmuti; ko si eyiti a ko gbo ri ninu gbogbo ọrọ ti a ka silẹ yi, ṣugbọn nigbati oyinbo—ani Oyinbo funfun tọn npe Enia Dudu to wa nilu Enia Dudu ni alejo nibẹ, ọrọ na ko ha pa ẹsi jẹ baun?

Ọgbẹni Lieutenant Colonel Harry Claude Moorhouse, R.A., C.M.G., D.S.O. oyinbo ni; ipo rẹ ninu iṣẹ ọba lo tẹle ti ọlọla Donald Cameron, igi iwe, oninurere, ati olotitọ, igbakeji Gomina wa, Sir Hugh Clifford—ẹniti o fun wa ni anfani nla ati yan enia mẹta si Igbimọ Aṣelu, ti a si tanma pe ko ni siregun, ko si ni loṣo ti ore to ṣe fun wa yi ni ọtunla, February 11th ninu ọrọ rẹ (Address) ni ajọ Igbimọ nla, Legislative Council.

Colonel Moorhouse wo iṣẹ ọba ni ijọ kerin oṣu September, ọdun kejilelogun, September 4th, 1902, owo rẹ nisisiyi jẹ egbejila pound, £2,400 lọdun laika ẹgbẹta pound £600 to ngba fun "Quarters and Duty Pay." Itumọ *Quarters* ni ile, nitorina oyinbo yi ngba ọwo lọto fun ile ọba to ngbe; Ẹ ko wa ri wayi bi Ijọba ti fi ara rẹ joye Pẹulẹpẹ, alowo ma mọ na.

Itumọ "Duty" ni ede oyinbo ni "Iṣẹ;" "Duty Pay" si jẹ owo iṣẹ. Njẹ bi ẹgbẹta pound £600 ti Colonel Moorhouse ngba lọdọdun ba jẹ "Duty Pay" tabi owo iṣẹ nitotọ gẹgẹ bi itumọ rẹ, egbéjila pound, £2,400 miran to tun ngba lọdọdun nkọ? Boya iyẹn owo Ere.

Bi otọ ba de, ki irọ salo: O dabi ẹnipe awọn oyinbo papa ro pe iṣẹ ti ẹnikan kan wọn nṣe nilẹ yi, lẹhin ti nwọn ngbe ile ọfẹ, ti ilu si nsan owo ọkọ talọ tabọ wọn lọ si ilu oyinbo, ko ju eyiti a le san owo ti awọn ngba gẹgẹ bi "Duty Pay" lọdọdun fun alọ, ati pe owo tiantian bi egbejila tabi ẹgbẹdogun pound ti ẹlomiran ngba lọdọdun lẹhin na ninu wa dabi ẹsẹ aṣiwere ti awọn Saro npe ni "Craze-man foot."

Ti a ba ti yọ owo ọgbẹni Henry Carr, Ba[…] kuro, ko tun si akọwe Enia Dudu miran ni[…] yi to ngba owo iṣẹ tan, to si tun ngba eni "[…] Pay" si loṣoṣu, bi igbati ọmọde ngba eni ak[…]

Ọrọ "Duty Pay" ti awọn oyibo ngba [...] yiyẹwo daradara lọdọ awọn aṣoju wa mẹta t[…] ni Igbimọ. Bi nwọn ko ba le pa "Duty Pay[…] fun Oyinbo, o yẹ ki Ijọba bẹrẹsi fun awọ[…] ọgbẹni Joseph Macwen, J. H. Stanley Rob[…] Torto, Carew, Ibarẹ Akisan, A. G. R. Nylan[…] J. N. Reffell, Solomon, Adedeji Iṣola, C. Bri[…] Davies, G. N. Martins, J. H. G. Willough[…] D. T. Ṣaṣẹgbọn, Victor Coker, C. B. Olumuyiw[…] Nelson Scott, C. W. Faulkner-Shaw, J. Julius *ali[…]* Apena, Boardman, A. S. Coker, H. M. Wee[…] I. Benjamin-Byass, J. D. Akihanmi, J. [...] Ahmad-Din, N. Fẹhintọla Williams, S. J. Marsh[…] J. T. N. Caulcrick, Wey, Taylor, John Forsythe[…] Falaṣẹ, I. O. Gilbert, Chief Dispenser Phi[…] E. O. Oke, T. A. Thompson, H. S. A. Tho[…] ati awọn ọmọ wa miran to wa ni ipo patak[…] iṣẹ ọba.

Lieutenant-Colonel Moorhouse gba isimi, [...] san owo ọkọ rẹ lọ si ilu Oyinbo titi yio si fi pad[…] ni ilu yio ma fi owo rẹ sowo si i loṣoṣu ni it[…] Crown Agents. Dipo eyiti iba de ilu rẹ, ti iba [...] owo to jọju lọ si Ṣọṣi lati lo fi dupẹ lọwọ Olọr[…] fun ipo nla ti on de ni ilu Enia Dudu, ko si tọr[…] adura pataki fun Enia Dudu—ilu ẹniti o di ẹni nl[…] ati enia pataki ti o si ngba owo ribiribi, nigbati [...] jẹ, ti o mu tan, ni "Nigerian Dinner" ni il[…] Oyinbo, bobo lọ bẹrẹsi sọ nipasẹ ọrọ enia mẹta ti ilu yan si Igbimọ Aṣelu. O ni ko si ẹnikan ṣoṣo ninu wọn ti a bi, ti a si tọ ni ilu Nigeria ti wa yi.

Mo ṣebi ọrọ ti oju enia ba to lo nsọ. Ọlọla Loya Eric O. Moore lo ha sọ pe East End ni ilu oyinbo ni nwọn bi on si, tabi ọlọla Loya Shyngle ati ọlọla Dokita Jones lo wipe ilu Tatambulu ni a fi ori wọn sọ'lẹ si? Ẹgba "Ọmọ Liṣabi" faufau ni Olawolu Moore, Ijeṣa lo bi Olaubiwọnnu Shyngle, Ọyọ ni ti Adeniyi Jones. Ewo ni ko si ninu Nigeria ninu ilu wọnyi?

Ka tilẹ wipe otitọ ni ọrọ ti Colonel Moorhouse sọ pe a ko bi ẹnikẹni ninu awọn ti ilu yan si Nigeria nibo ni Oyinbo yi wa nigbati awọn ọga rẹ nṣe ofin nipase ẹniti a le yan sibẹ, nibo lo wa nigbati awọn Oyinbo meji tabi mẹta nrọ ilu pe ki o dibo fun wọn? A ko bi oyinbo Harvey si Idumagbo, bẹni oyinbo Mulford ko nṣe ọmọ Isalẹ Eko tabi Mẹkunẹ.

Colonel Moorhouse papa, ilẹ yi ni nwọn bi si, tabi a ko ha gba sọwọ, gba sẹsẹ lati igbati o ti wọ ilu. Ti a ba le ṣe eyi fun alejo, melomelo lo ha yẹ ki a ṣe bẹ fun ara wa. God save the *King!*

## BI UWOLE, OLOYE NLA, B.A., D.D.

ia lo ngbadura ki alẹ wọn dara ju ; sibẹsibẹ ko si ẹniti ko fẹ ki ire ẹlu on lati owuro titi di alẹ. Ẹlomi-ṣẹ titi, ti aseko ati jẹ adun gbogbo de, nigbana ni iku ma yọ si gbẹrẹ, o ji aremabọ. Ẹlomiran ẹwẹ, ti o nwọ si Ikorodu ati Ejinrin lati lọ ṣowo, ọla, o padanu, ijọ ti o ba si jaja ri ri ere jẹ, ijọ na ni on ati owo ati ẹru wọ—ni gbogbo wọn ma ṣe yakata si omi Langbasa.

mọ ti Iya tabi Baba ẹlomiran gbẹkẹle, ọsan gangan, elomiran a pade agbako iro ; orişirişi idanwo bayi lo kun aiye tonẹ ntu ara wa ninu pe itunọ agbalagba ni ẹniti f' ara gba inira ati işoro aiye.

nu gbogbo idamu ati imulẹmofo aiye yi, a pe Ọlọrun ndabobo wa lọsan ati loru. Ti a okun fun odidi ọjọ kan, O nfun wa ni ayọ ni nijọ keji. Bişọpu Oluwọle sọkun ri, o sọkun obi re ti ko si, o sọkun iku ọmọ, o s kun o ti Şọşi Breadfruit daru lọdun kẹrinlelogun o kẹdun işubu ati iyapa onigbagbọ, şugbọn hkọ? Bi irun ori rẹ ti funfun to bẹni ehin rẹ mun nigbati o ba nrẹrin.

wo ni ko to ayọ ninu tirẹ, ogunlọgọ awọn ti o ni fun, ti o gbọwọ le lori, ti o fi jẹ oye Alufa ni, oi awọn ọmọde ti o ti ko li ẹkọ ti nwọn si wa ni o giga loni, ipo ti Ọlọrun fi awọn ọmọ rẹ papa si tabi ifẹ iyebiye ti on pẹlu oburo aya rẹ to dabi undia ni si ara wọn, ẹmi gigun ti Ọlọrun fi ta on papa lọrẹ ni tabi Ajidewe awọ ti o ni, ewo ni ko o ayọ ninu gbogbo wọn.

(O te oşu merin nisisiyi ti Ọgbẹni G. Debayọ Agbebi, C.E., B.SC., F.G.S. gbe iwe sode lati gba owo lọwọ ẹnikẹni to ba wu ninu awọn "*old boys*" tabi ọmọ ti o ti kowe ni Ile-iwe giga ti Grammar School ri fun aworan Bişọpu Oluwọle, ẹniti o ti nşe oluko agba, (*Principal*) ni "Şukuru" na ni iwọn ọdun marundi-ladọta sẹhin ki a to fi jẹ oye Bişọpu ni iwọn ọgbọn ọdun ti o kọja. Ayan ati wahala nla ni Agbebi şe si oran yi, ki o to ri owo kojọ, ninu eyiti a fun Ọgbẹni Aina Ọnabolu ni adọrin ponwun, adọrin şile (*Seventy guineas*) fun aworan Bişọpu kanşoşo na ti o ya.

Ni alaruba ijẹrin, Wednesday, February 6th, ni a pe ọpọ enia jọ si Ile-iwe Grammar School ni agogo marun aşalẹ, lati wa nibẹ nigbati a o fi aworan yi ta Bişọpu lọre. Ile kun, ọna bo, burẹdi pẹlu ọti alagbayun (*Ginger Ale*) ni awọn ti a pe fi pa'nu nibẹ. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, L.TH. li o wa lori aga ; inu rẹ si dun tobẹ ti ko fi le sọrọ pupọ. Ngbọ? Ogunbiyi ha lẹ gbagbe akoko ti Bişọpu ngba on nigi lọwọ nitori Jọgrafi (*Geography*) ni Şukuru, ti o si tun pada di Archdeacon Eko li oju Bişọpu kanna, ti o si nwo Charlotte ọmọ rẹ li okankan li ẹgbẹ Dokita Ladipọ, ọmọ Bişọpu Oluwọle, gba-gba-gba ni ijẹrin, talo ma şe, ti inu rẹ ko ni dun—iba şe iwọ nkọ?

Ọrọ ti Bişọpu sọ ni ijẹrin dara, o si wu ni lori lọpọlọpọ. O kan sara si pupọ ninu awọn ti o ti kọ li ẹkọ, ti nwọn si wa ni ipo giga loni, awọn bi ọlọla Loya Eric O. Moore, J. T. Nelson Cole ati J. H. Stanley Robbin.

Ọpọ enia li o wa si apejọ na, Alufa A. N. Cole ti o wa nibẹ pẹlu mu wa ranti Ologbe Rev. T. B. Macauley baba Ejongboro, ẹniti o şe oluko agba ni Grammar School şiwaju akoko Bişọpu Oluwọle. Ẹni mẹta pere ni a ranti wipe o wa laye li Eko loni ninu awọn ti Alufa T. B. Macauley kọ li ẹkọ ni Grammar School ; awọn mẹtẹta na ni Alufa A. N. Cole, Ọgbẹni D. Towry Coker ati Tommy Macauley ti olowogbowo. Ẹnikan şoşo pere ni a si ranti wipe o ku ninu gbogbo awọn ọmọ ti o ba wọn bẹrẹ Grammar School ni akọkọ bẹrẹ, oluwarẹ na ni Archdeacon Dandeson Crowther.

Ọgbẹni Aina Ọnabolu şe ponpọn işẹ si ara aworan Bişọpu Oluwọle to ya, şugbọn aworan na jọ Bişọpu pupọ lokere ju isunmọ lọ.

K' Olorun tubọ fi ẹmi gigun ati alafia ara ta Bişọpu Oluwọle ati gbobgo wa lọrẹ o.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ATARI-AJANAKU

---

### WONDERS OF A GREAT FIRM.

As will be seen in our advertisement columns—the opening of Lever Stores Limited, takes place on Tuesday February 12th 1924.

We have had the pleasure of inspecting this fine store in Broad Street, and the terms used in their advertisement "Splendid Assortment" and "Wonderful Value" are certainly modest ones.

The name of the Company in itself will ensure it a very hearty welcome among us, knowing as we do the fine business traditions connected with the name Lever—a household one not only in West Africa but all over the world.

Lever Stores Limited are fortunate in having as Manager, a gentleman so well-known and respected as Mr. Hopkins. That his many years among us have not been wasted is plainly shown by the wonderful collection of the "ju what we wanted" articles that the Lever Store has to offe.

The goods in the store are plainly marked and laid out o display counters, a separate counter for each section—3d. 6d. 9d 1/- and until the advent of Lever Stores, Limited, it would have been thought impossible to offer such variety and value at these low prices.

Another feature of the Lever Store is the "Soda Fountain" —again something new to us. Here can be obtained non-alcoholic fruit flavoured cold drinks at 3d per glass, which we have no doubt will be well patronised.

We predict for Lever Stores, Limited, the wonderful success that such enterprise deserves.

Si Oni 'we-irohin, "EKO AKETE."

ALAGBA,

Jọwọ ma ṣai gba mi ni aye diẹ kiun ninu iwe irohin rẹ lati fi ẹnu ba ọrọ kan ti a gbọ pe alasoye kan sọ nibi ipade awọn Atẹkate Ijọ Ajeji nipa orin ilẹ wa, ati Ilu ti a nlu si i eyiti o pe ni Batakoto.

Ohun kini, ọpọlọpọ ni ko mọ iyatọ larin awọn ilu wọnyi. Lotitọ sise wọn le dogba ṣugbọn lilu wọn lo nya tọ t a si fi nfun wọn loruko ọtọtọ, eyi lo jẹ ki a ni Dundun, ati Apọnran, Gangan Bembẹ, Batakoto, Agerẹ ati bẹ lọ. Ẹgba jẹ pataki kan ninu awọn alaṣẹ ilu wọnyi nipataki Batakoto ati Agerẹ, eyiti wọn si nlo fun isin yi ni lilu ati sise papa Agerẹ on lo si jẹ ilu ti o ni ọwọ ju larin awọn Ẹgba tobẹ ti o fi jẹpe ti awọn onigbagbọ ba nlu u yi ode lọ, awọn pataki ti o le ri nibẹ ni obinrin, bi o ba si ri awọn ọkọnrin, nwọn a jẹ awọn ẹni ọwọ, ẹni aiyesan ati agbalagba nipa eyi ọwọ pupọ lo wa fun ilu yi ti a ko fi ba jẹ bi awọn ti o ku ti awọn ti o si da a pọ mọ isin fi ro pe on lo to fun isin pẹlu ọwọ ti o ti ni lara tẹletẹlẹ, ọla rẹ yio ma re iwaju ni.

Ekeji, nitori ti awọn Dutch ti ṣe iru orin isin awọn bẹ ri ti ko si mọ loni nitorina o le sọ pe ko yẹ, ṣe owe wa kan sọ pe, Ẹnito jin si koto kọ ẹni ti o ku l' gbọn ni. Ki iṣẹpe ki a ma gba ibi koto rora koja nibẹ ambutori ọran koto kọ ni eyi, ọran atọsanbabaja si ko, ọran a ba laiye, abinibi ni Ethiopia ko le pa awọ rẹ da. Ki iṣe orin ti Gẹsi gba lọwọ Aguda ni nwọn nlo titi di oni.

Ẹkẹta, o ri awọn Ijọ kan nfi ọrọ mimọ sinu orin aimọ sin Ọlọrun, o dun mọ ni pe Ojiṣẹ Ọlọrun kan la' gbogbo rẹ ye wọn bi o ti ṣe pe a ko le ṣalai ni orin ti ile wa, ṣugbọn a ni lati mọ lo jẹjẹ, a ki i bimọ lojọ ko dagba lojọkanna. Ninu orin ti a nlo titi di isisiyi a le yo meji, mẹta jade ninu rẹ ti iṣẹdalẹ wọn jẹ orin aimọ. Ede wa lọna miran jẹ ede ti sisọ rẹ jẹ orin, eyi ni ko jẹ ki a ma ranti pe a ko ṣe alaini orin pataki fun isin Ẹlẹda ti awọn enia wa ninu aimọ wọn ko je lo ni ilokulo. Bi a ti le so orin ti o mọ di alaimọ nipa ilokulo rẹ, bẹ a o le sọ alaimọ di mimọ pẹlu nipa ọwọ ti a ba tun fun u. Eyi ni Ọgbẹni T. K. E. Phillips akọrin Afuduru Christ Church, ri ki o to ke si awọn enia laipẹ yi pe ki a fi ọwọ ti o yẹ fun orin Keresimesi sibẹ Ọgbẹni na ko le sọ pe ko ye ki a ma ni ohun orin ni ede tiwa. Awọn ọjọgbọn ninu imọ doru ati orin ni lati sa ipa wọn lati ran awọn ti o nfi iru ifẹ ilọsiwaju ohun ti iṣe ti Enia Dudu han lọwọ, dipo eyiti nwọn i' ba ma fi bomi pa ayan awọn enia ti Ọlọrun fi si l' ọkan lati ma ṣe e, ni igbagbe pe "Etẹ awo ni etẹ ọgbẹri."

Tani ọkan rẹ ki yio fa si idi Itẹ anu nigbati o ba ngbo iru orin bi :—

" F' ifẹ s'n Ọlọrun, ẹnyin t' o kunlẹ
Ifẹ otitọ ni k' a fi josin
K' Ọba ti ngbe ọrun, ibi mimọ l' oke
Le wa tẹwọgba isin wa s' oke.

(¾ TIME)

d | s : — : m : — : s | r : — : — ‖ d | r : — : m : — : m | d : — : — ‖
s | d : — : s : — : d | d : — : — ‖ l | d : — : l : — : d | s : — : — ‖
[2 times]

m | m : — : s : — : s | d : — : r : — : — ‖ s | s : — : l : l : l : r : — : — ‖
d | s : — : s : — : s | m : — : — ‖ d | r : — : m : — : m | d : — : — ‖

Wo bi ọrọ orin papa ti ba wa l' arajọ pẹlu ohun orin na.

Oluwa jẹ ki akoko na tete de ti gbogbo wa yio le ma yin Baba ni ede ati orin wa.

Apẹrẹ nla iṣẹ ti orin nṣe wa larin awọn Oni Bori (oriṣa kan) ni 'lẹ Hausa, eyiti bi awọn alun fe ati oni molo pẹlu awọn akọrin ba bẹrẹ si ko orin ẹniti o njo a wu tobẹ ti yio si ma bẹrẹ si gbe a rẹ wọnlẹ ni isin oriṣa rẹ, tabi eyiti a npe ni oriṣa gun u. Nigbọn igba ti orin ba le ṣe ohun ti o to eyi fun awọn ti a rope ko mọ iyi orin ati isin Ọlọrun totọ melomelo ni yio jẹ iwuri fun wa bi a ba le fi ọwọ ilaju ti wa mu u.

Nipa ti Ilu ẹwẹ, iba dara bi oṣe pe alasoye na fiyesi pe pẹlu ami ni a fi nlu awọn ilu wọnyi, ati pẹlu nigbamiran agogo nikan ni ...fi pẹlu orin miran bi iru ti dke yi lati fi iyin ... ti Ironu Ibọlọwọ Ijuba ati ti Iyin ... Ịẹnu iṣẹ ... Ẹnu ya ni lati gbọ pe ariwo lo ... ijuba pọ na pẹlu gbogbo mimọ rẹ. Bi o si ti jẹ ariwo orinkorin ti o wu ki awọn Akọrin Christ Church le ma kọ jẹ ariwo ti o bori ariwo leti awọn aboriṣa ti o ṣẹṣẹ ngbagbọ.

Gbogbo iwọnyi fi han wa pe ohun tiwa ko nkun wa loju rara, o yẹ ki a ma ranti nigbagbogbo pe orin ilẹ wa ko le ṣalai fi igbọnwọ kan dun leti wa ju ti ilu miran lọ, bi o ti ṣe pe.

Orin jẹ idapọ iro afẹfẹ ti adalu rẹ fun eti ni igbadun.

Mo dupẹ fun aye ti o gba mi, ọwọ yio r' oke o.

OKE ỌNA.


H. S. Freeman

(Photographer-in-Chief to His Excellency the Governor of Nigeria.)

Dealer in all kinds of Photographic Materials

Films, Post Cards, Views etc., etc, on hand.

"Also films undertaken for development."

Satisfaction Guaranteed

Office :—106, TOKUNBO STREET, LAGOS.

Telegraphic address :—"FREEDE" LAGOS.

P. O. Box 495.

## *Preachers for To-morrow.*

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC. (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ,
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Bishop of Lagos |
| 6.30 p.m. | do. | Rev. C. A. Ṣowunmi |
| [illegible] a.m. | —St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St. Peter's (Alapako) | Rt. Rev. Bp. I. Oluwole |
| 6.30 p.m. | | (In charge) |
| 9 a.m. | Holy Trinity (Ebute-Ero) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| [illegible] m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |
| | | do. |

**WESLEYAN**

| | | |
|---|---|---|
| [illegible].30 a.m. | Tinubu | Rev. E. G. Nightingale |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. H. Loko |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. M. O. Dada |
| 7 p.m. | do. | Rev. D. A. Beckley |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. N. A. B. John |
| 7 p.m. | do. | Rev. Mellor |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. J. F. Kufeji |
| 7 p.m. | do | Rev. D. O. L. Mojọla |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Rev. G. A. Oke |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. A. Laleyẹ |
| 9 a.m. | Erelu | Bro. A. M. Williams |
| 7 p.m. | do. | Bro. Ọlaboye Laleyẹ |
| 9 a.m. | Christ Church (Ebute Mẹta) | Bro. V. E. Ọlaleyẹ. |
| 6.30. p.m. | do. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Bethel | Rev. E. A Akiola |
| 6.30 p.m. | | „ E. D. Ṣodẹinde |
| 6 a.m. | Zion | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. E. A. Williams |
| 4.30 p.m. | | Rev. I. O. Oyekunle |

**FIRST BAPTIST CHURCH**

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | |
| 6.30 p.m. | | |
| 9 a.m. | Araromi (Baptist) | Rev. E. C. Alabi |
| 6 p.m. | | Bro. S. M. Phillips |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. S. M. Philips |
| 6.30 p.m. | Bro. Joseph Bandele |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m. Ilupesi. | Resp'table Bro. Arinọla Ọkọya |
| 7 p.m. | Prof. Adeoye Deniga |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

| | |
|---|---|
| 6 a.m. | Fajir Service I. A. Shitta |
| 5.30 p.m. | Open Air Service Imam K. R. Ajoṣẹ (Bamgboṣe Street.) |

**COLONIAL CHURCH. (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

**SALVATION ARMY.**

10 a.m. Glover Memorial Hall Capt. A. A. da Costa
7 p.m. Lieut. Colonel George H. & Mrs. Souter

**CHURCH OF GOD**

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m Open Air Service at Campbell Square, Edwin Mathew & Wm. C. F. Terrell.

---

## IGBẸ L' OWO WÀ.

Bi awọn Oyinbo Oniṣowo ilẹ yi ti gba awọn Ọja wọnyi si l'ọsẹ yi ni eyi :—

EKURỌ

£16—£16 10 fun *ton* kan

EPO.

£26—£27 fun *ton* kan.

COCOA.

£18—£18 10 fun *ton* kan.

---

KANO

ẸPA.

£14 15—£15 fun *ton* kọkan.

AWỌ (*Skins and Hides.*)

Skins 1/9d fun lb kọkan.

Hides 5d fun lb kọkan

**FRIENDS and COUNTRYMEN,**

**LET US SEIZE THE OPPORTUNITY OF THE DAY.**

Become a certified Medical Herbalist and learn how to alleviate human suffering by the skilful use of

***NON-POISONOUS HERBAL REMEDIES.***

The British College of Herbal Medicine of Bolton, England, prepares students to qualify as certified HERBALISTS by studying their Correspondence Course of Lessons.

**For full particulars, apply to the Official Representative of the College :—**

C. GLADSTONE-MACAULAY,
P.O. Box 384,
Lagos, Nigeria, W.A.

**Remember that :—**

*The more you know, the more you know how little you know.*

---

# Chairs ! Chairs ! ! Chairs ! ! !

## For hire at Ilupesi Hall, Enu-owa, Lagos.

REDUCED PRICE, 1½D. PER CHAIR, PER DAY.

Apply to the MANAGER,
J. A. OSHODI,
26, OBUN-EKO SREET,
LAGOS.

---

# AGA, AGA, AGA.

FUN YIYA NI ILUPESI, ẸNU-ỌWA, LI EKO.

OWO PỌKU NI A FI NYA NI NISISIYI, (1½D.) KOBỌ KAN PẸLU ABỌ.

Lọ si ọdọ ALABOJUTO,
Ọgbẹni J. A. OSHODI,
NO. 26, ITA OBUN-EKO,
LI EKO.

---

# The Kaduna Store,

## 75 & 81, ODUNFA STREET,

*near Mr. A. W. Thomas's palatial residence.*
ẸBUN HOUSE, LAGOS.

begs to inform all Cyclists and Motorists to buy always at our Store, complete spare parts and accessories for all makes of Motors, Bicycles, etc.

Established 1921, we have much pleasure to say that we have added to our STORE, Goods to the tune of £200, being expert in the repairs of Motor-cars, Bicycles and all other machinery. We specialise in the purchase of old Cars, Bicycles, Gramophones which are minutely repaired by us and in turn, sold to those unable to afford high price, at giving-away prices, viz :—£3 £4 £6 10s. respectively, according to durability and taste.

For particulars, apply to the Proprietor :—

SAM ADE : CLAY of the above address, or at 1, Macaulay Street, Lagos.

TERMS :—Cash with Orders.

---

## ILE OWO KADUNA,

to mbẹ lẹgbẹ Ile-afin Ọgbẹni A. W. Thomas ni 75 ati 81, Ita Odunfa, (Anikantamo) L'Eko.

Awa ni orișirișí Kẹkẹ-ologere ati Kẹkẹ pupu-pupu ni tita, a si ni awọn " Ero-ija Oloj Ọlọla wọn pẹlu.

Lati ọdun 1921 lati wa lẹnu iṣẹ n mu awọn ọja wa si to ọja o ni igba pọ̀. (£200.) Ko si bi Kẹkẹ-ologere kan t awọn ti pupu-pupu kan ti le bajẹ to ki a ... s gbe'ro : a si nra awọn "oku" Kẹkẹ-ologere, oni-pupu-pupu, ati Ẹro-akọrin (*Gramophone*) ti a ntun șe ti a si tun nta lowo pọ̀, bi £3, £4, £6 10 fun awọn ẹniti ko ba to pẹmu olowo-nla ru.

Ẹ wa tabi ẹ kọwe șọwọ si Olotu Ile-owo yi :—Ọgbẹni SAM ADE CLAY ni adugbo ta darukọ loke yi, tabi ni No. 1, Ita Macaulay (Okepopo) l'Eko. Owo lọwọ ni gbogbo Ọja rẹ o, aibamọ.

---

**CHANGE OF NAME.**

I the undersigned formerly known and addressed as

TIAMIYU ABIODUN LAWANSON

of 2, Hotonu Street, Lagos, Nigeria, hereby beg to inform friends and the public in general that on and from the 1st day of February, 1924. I desire to be known and addressed as.

THEOPHILUS ABIODUN ONITIRI

All documents bearing my former name remain valid.

*17th Jan, 1924.* T. A. LAWANSON.

# A. KESSLER,

7, Labinjọ Lane. P.O. Box 459.

SAMPLE SHOW ROOM.

*Agent for* ARNOLD SCHLESINGER.

The German Trading House.

Hamburg, Germany.

SAMPLES OF ALL GOODS FOR THE AFRICAN MARKET EXHIBITED.

The Mundlos Hand and Foot Sewing Machine as well as the Alder Foot Sewing Machines.

*Are always obtainable from stock or for order and are ornaments for everybody's house.*

FOR SALE.

The Typewriter "Berkeo" ... £9. 5. 0.

Cycles

Toys, that is what you want for Xmas.

24 hours Kitchen Clocks—a good clock for a good time.

Earthenware.

Descent Wristlet Watches ... 8/- and 4/3 each.

Carpets to make your house comfortable.

Clay Pipes, Razors, Fez Caps, Hanging Lamps etc.

As the fire wants the wood to burn, you want my Beer to quench your thirst, therefore buy the

LION BEER (Pilsener Light) 30/- per case.

TUCHER BEER do. 34/- per case.

And for happy hours take a case of my requisite

CHAMPAGNE per case £3 5 0.

# JACOB AJAYI,

## *General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

**Prices to suit everybody.**

*Call now, fortune awaits you.*

## Aworan Alarabara.

A ni Aworan oniruru fun tita lati fi ṣe ile li ọṣọ. A ni ti titẹ oku Jesu, ti igbati a da a li ẹbi iku, ti Onjẹ-alẹ ikẹhin. A ni ti Adamtati Efa, ti iṣọdalẹ aiye, ti Nebuchadenezar nigbati o wa ninu ọla rẹ, ati nigbati o di ẹranko; ti obirin ti o fi ọwọ mu ejo, ati ti Ọba Tatambulu.

A ni ewe Taba fun [illegible] ti Ọṣẹ Olowo—[illegible]; Iyọ-iyọ mbẹ lọwọ wa fun tita bi wọbu, bi o ba fẹ ẹ ni *iponu* a le ta a fun o. Iṣana Alapoti fun tita, ko si bi a ti nṣe wọn. Orișiriși ọja lo wa lọwọ wa, iwọ ko le ba wa ṣowo ko ma jere tirẹ, nitori owo poku ni a nta wọn. Owo ọja wa rọju rekọja ala. Bi o ba wa si ile-ọja wa "Ka mi, ka mi, ka mi" ni gbogbo wọn, bi o ba fẹ ja iro wa, rin wa si ile ọja wa.

Iye owo wọn:—3d, 4d, 5d, 6d, fun ọkọkan; 2/6d, 3/-, 4/-, 5/6d fun mejila.

Ibikibi ti o ba ngbe ni *Nigeria* tabi ẹhin okun kọwe ṣowọ yala ni ede Gẹsi tabi ti Yoruba si:—

E. O. AMBE & BROS.,
38, Moloney Bridge Street, Lagos,
*( Ledge awọn Ọniṣowo A. J. Tangalakis ).*
Idumagbo, Eko.

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay,

88, BROAD STREET.

Wabiwosi orișiriși Egbogi lo ṣeṣẹ de fun wa ni tita: awọn bi:—ogun Egbo orișiriși, ogun Ẹda, ogun arun aṣiri, ogun Arẹmọ, ogun Onigbamẹji, ogun Aran orișiriși, ogun Lakuregbe, ati awọn ogun miran ti a ko le mã to lẹsẹsẹ.

Ọpọku-ọyọku ni owo wọn, nwọn si jẹ bi idan.

Ọrẹ, ẹ lọ dan awọn Ogun wonyi wo nibi ti a gbe nta wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.